UK Health Security Agency

NHS

# Bí o ṣe le dáàbòbò ọmọ rẹ lọ́wọ́ RSV

## Ìtọ́nisọ́nà sí abẹ́rẹ́ àjẹsára Respiratory Syncytial Virus (RSV) fún àwọn obìnrin tó lóyún



**Àwọn obìnrin tó lóyún le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fẹ́ ní oyún kọ̀ọ̀kan, láti dáàbòbò ọmọ wọn lọ́wọ́ Respiratory Syncytial Virus (RSV).**

## Kíni ìdí tí a nílò láti dáàbòbò àwọn ọmọ lọ́wọ́ (RSV)?

Respiratory syncytial virus tàbí RSV jẹ ààrùn àìlefojúrí kan tí ó le fa àrànmọ́ ẹ̀dọ̀fóró tí à ń pè ní bronchiolitis. Nínú àwọn ọmọ ọwọ́ ipò yìí le jẹ́kí ó le láti mín àti láti jẹun. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ ló ṣeé mójútó ní ilé sùgbọ́n bíi 20,000 ìkókó ni a gbà sílẹ̀ sí ilé-ìwòsàn pẹ́lú bronchiolitis lọ́dún kọ̀ọ̀kan ní England. Àwọn ìkókó tóní bronchiolitis líle le nílò ìtọ́jú kíkankíkan tí àrànmọ́ náà sì le gboró/pa ni. Ó seéṣe kí RSV gboró nínu àwọn ọmọ ọwọ́, àwọn tí osù wọn kò pé, àti àwọn tóní ipò tó ń kóbá ọkàn, mínmín tàbí ètò àjẹsára wọn. Àwọn àrànmọ́ RSV le wáyé jákèjádò ọdún sùgbọ́n àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ náà ga jùlọ ní gbogbo àkókò òtútù.

## Bawo ni RSV ṣe nran?

RSV má ń ràn gidigidi ó sì má ń tètè tań kiri, pàápàá jùlọ láàrin àwọn ọmọde, nípasẹ̀ wíwúkọ́ àti sínsín. Kódà pẹ̀lú àwọn ìṣe tó rọrùn bíi ọwọ́ fífọ̀ àti bíbo ẹnu àti imú rẹ nígbàtí o bá sín, ó sòro láti yàgò títàn ìrànmọ́ náà kiri láàrin ìdílé. Ọ̀nà tó dára jùlọ láti dáàbòbò ọmọ ọwọ́ rẹ lọ́wọ́ àrànmọ́ RSV ní kí o gba abẹ́rẹ́ àjẹsára l'ásìkò ìlóyún.

## Bawo ni abẹrẹ ajẹsara RSV ṣe munadoko si?

Àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára náà ń ru ètò àjẹsára rẹ sókè láti pèsè ọ̀pọ̀ àwọn àjẹsára tako ààrùn àìlefojúrí. Àwọn àjẹsára wọ̀nyí yóò wá gba ibi ọmọ kọjá láti bá ọ dáàbòbò ọmọ ọwọ́ rẹ láti ọjọ́ ìbí wọn. Ètò gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára ń dín ewu bronchiolitis líle kù bíi ìwọ̀n 70 nínú 100 ní osù 6 àkọ́kọ́ l'áyé. Lẹ́yìn ọjọ́-orí yìí ọmọ owọ́ rẹ wà ní ewu RSV líle níwọ̀n. Àwọn ọmọ tó dàgbà àti àwọn àgbàlagbà tún le ni àrànmọ́ RSV, sùgbọ́n ààrùn náà le púpọ̀jù fún àwọn ọmọ kékeré àti àwọn ènìyàn ọlọ́jọ́ orí 75 s'ókè.

## Nígbà wo ni mo gbọdọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára?

A gbọdọ̀ fún ọ ní bíi àkókò ìgbà ìpàdé olóyún ọ̀sẹ̀ 28 rẹ. Bí o kò bàá tì gbàá ní ìpele yìí, kànsí iṣẹ́ ìgbẹ̀bí tàbí dókítà rẹ láti ṣ'èto ìpàdé kan. Gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára ní ọ̀sẹ̀ 28 tàbí láàrìn ọ̀sẹ̀ díẹ̀ yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ní ìpele àwọn àjẹsára dídára láti fi sọwọ́ sí ọmọ rẹ sáájú ìbí. Èyí yóò fún ọmọ rẹ ní ààbò dídàra jùlọ, pẹ̀lú bí o bá tètè bí wọn.

O sì tún le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára tóbáyá ní àkókò ìlóyún sùgbọ́n o le má múnádóko dáradára. Kò séèṣe láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ kíákíá, a le fún ọ ní kété tí o bá bímọ. Bí o bá níi tóbáyá ni àkókò ìlóyún, ó sì le dáàbòbò ọ́ lọ́wọ́ àrànmọ́ kí ó sì dín ewu títan àrànmọ́ kàá sí ọmọ tuntun rẹ.

## Njẹ maa ni awọn idiju kankan?

A ma nsaba funni ni abẹrẹ ajẹsara ni oke apa o si le ni oju ọgbẹ kọọkan, ara pipọn tabi wiwu ni oju abẹrẹ naa. O tun le ni ori fifọ tabi isan riro fun ọjọ 1 tabi 2.

Ninu awọn agbalagba, wọn ti jabọ ipo eto isesi ara to nyọri si rirẹ, eyiti a mọ si awọn aami isajeji Guillain-Barré syndrome, wipe o **sọwọn gidigidi** lẹyin eto abẹrẹ ajẹsara. Ipo kanna le tun sẹlẹ lẹyin iye awọn aranmọ to wọpọ ati awọn abẹrẹ ajẹsara diẹ. Ipo naa ko wọpọ daradara laarin awọn ọdọ ati, titi di isisinyi, kosi ifidimulẹ wipe abẹrẹ ajẹsara RSV n mu ki ewu aami isajeji Guillain-Barré gberu sii ninu awọn obinrin to loyun.

## Ǹjẹ́ gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára RSV l'ásìkò oyún kò léwu fún ọmọ mi?

A ti ṣe ìwádìí abẹ́rẹ́ àjẹsára náà nínú àwọn ìdánwò ìṣègùn tí àwọn obìnrin bíi 4,000 tí a sì ti fún ọ̀pọ̀ ẹgbẹ̀rún àwọn obìnrin nínú àwọn ètò orílẹ̀-èdè. Ìmọ̀jútó ní USA, níbití a tí fún àwọn obìnrin tó ju 300,000 lọ, ti sàfihàn ààbò ìkójọ ìwífúnní nípa ènìyàn dídára. Nínú ìdánwò ìṣègùn àkọ́kọ́, ní osù lẹ́yìn ètò gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára, àwọn ọmọ tí osu wọn kò pé pọ̀ díẹ̀ nínú ẹgbẹ́ abẹ́rẹ́ àjẹsára (2.1%) ju ẹgbẹ́ tí kò gba abẹ́rẹ́ àjẹsára (1.9%). Ìyàtọ́ yìí seéṣe kí ó wáyé látàrí ààyè. Àwọn agbófin ìṣegùn ró tí fọwọ́sí abẹ́rẹ́ àjẹsára náà ni UK, Europe àti USA lórí ààbò, àwọ̀mọ́ àti àìléwu.

## Ǹjẹ́ gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára túmọ̀sí wípé ọmọ mi kò gba RSV?

O tí hàn wípé abẹ́rẹ́ àjẹsára ti dín ààyè ìjìyà ọmọ rẹ kù kúrò lọ́wọ́ ààrùn RSV líle. Bíi gbogbo àwọn òògùn, kòsí abẹ́rẹ́ àjẹsára tó péye pátápátá tí àwọn ọmọ kan sì le tún ní àrànmọ́ RSV bíótilẹ̀jẹ́pé àwọn ìyá wọn gba abẹ́rẹ́ àjẹsára. Ẹwẹ̀, fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọmọ tí ìyá wọn ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára, èyíkèyí àrànmọ́ RSV kò gbọdọ̀ le.

O le ka iwe iwifun pelebe fun abẹrẹ ajẹsara RSV ti a npe ni Abrysvo nibi:
**www.medicines.org.uk/emc/product/15309/pil**

## Bí ọmọ mí bá wà ní ewu gíga?

Awọn ọmọ mìíràn tó wà ní ewu RSV gíga, bíi àwọn tí wọ́n osù wọn kò pé, àwọn tóní ààrùn ọkàn líle tàbí tóní àjẹsára tí kò lágbára le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára kan. Abẹ́rẹ́ yìíyóò pèsè àlékún ààbò lórí èyíkèyí àwọn àjẹsára tí wọ́n le gbà láti ọ̀dọ̀ ìyá wọn.

## Njẹ mo nilo lati gba abẹrẹ ajẹsara RSV ní gbogbo oyún?

Bẹ́ẹ̀ni, o gbọdọ̀ gbàa ní gbogbo oyun láti fún ọmọ tuntun rẹ ni ààbò tó dára jùlọ.

## Ǹjẹ́ mo le gba abẹ́rẹ́ àjẹsára àkókò oyún yòókù ni àkókò kanna tí mo gba abẹ́rẹ́ àjẹsára RSV?

Ó ṣe pàtàkì láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsára rẹ ní àkókò tọ tọ́ ní àkókò oyún:

- à má ń tètè fúnni ní abẹ́rẹ́ àjẹsára ikọ́ àwújù ní àkókò oyún (ní àkókò agbedeméjì àwòrán oyún, pàápàá jùlọ ọsẹ 20)
- o gbọdọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsára RSV rẹ bi oyun rẹ ba ti pe ọsẹ 28
- abẹ́rẹ́ àjẹsára ọ̀fìnkìn le jẹ́ gbígbà ní èyíkèyí ìpele oyún. O gbọdọ̀ gbàá ní kété tó bá ti wà lárọ̀wọ́tó rẹ

Nígbàtí a bá pè ọ́ fún abẹ́rẹ́ àjẹsára RSV, bí o kò bá tíì gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ikọ́ àwújù tàbí ọfinkin, o gbọdọ gba mejeeji lẹẹkannaa.

## Níbo ni mo ti le gba ìwífún síwájú síi?

O le bá agbẹ̀bí tàbí dókítà rẹ sọ̀rọ̀ o sì le ka ìwé pélébé yìí lórí ayélujára níbí:

**www.gov.uk/government/publications/respiratory-syncytial-virus-rsv-maternal-vaccination**

**www.nhs.uk/pregnancy/keeping-well/vaccinations**

Fún ìwífún síwájú síi lórí àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára tí a o fún ọ nígbàtí o bá lóyún ní o le rí ní:

**www.gov.uk/government/publications/pregnancy-how-to-help-protect-you-and-your-baby**

## Ǹjẹ́ ọmọ mi le gba RSV bronchiolitis?

Àwọn ààmì ààrùn RSV bronchiolitis le pẹ̀lú:

- imú sísàn tàbí dídí
- mínmín le, yára tàbí ńpariwo (mínmín gulegule)
- ìsòro ìjẹun
- ikọ́
- iba
- aìfarabalẹ̀ tàbí ìsoro ìrọ̀rùn
- rírẹ̀ tàbí àìlágbára

RSV tún le fa àwọn ipò yòókù nínú àwọn ọmọ wẹ́wẹ́ bíi ikọ́ àwújáde àti àrànmọ́ ìnira nínú etí.

O le jábọ̀ àwọn ìdíjú tí o furasi lórí ojú-ewé káàdì Yellow (Yellow Card) tàbí nípa pípe 0800 731 6789 (agogo 9 òwúrọ̀ si 5 ìrọ̀lẹ́ Ọjọ́ Ajé sí Ẹtì) tàbí nípa gbígba ápùù Yellow Card sílẹ̀ sórí Apuu.

**www.mhra.gov.uk/yellowcard**

## Bèèrè fún ìpàdé dókítà pàjáwìrì kan tàbí pe 111 bí:

- ọmọ rẹ bá ní ikọ́ tí ó sì ńburú
- ọmọ rẹ kò muyàn tàbí jẹun tó bí o ti yẹ
- ọmọ rẹ ti ní ìlédìí gbígbẹ fún wákàtí 12 tàbí jùbẹ́ẹ̀lọ, tàbí s'àfihàn àwọn ààmì omi ara gbígbẹ yòókù
- ọmọ rẹ kò tíì pe osù 3 tí ó sì ní ìgbóná tótó 38°C, tàbí ó dágbà ju osù 3 lọ tí ó sì ní ìgbóná tótó 39°C tàbí jùbẹ́ẹ̀lọ

## Pe 999 tàbí lọ sí A&E bí:

Ó bá dàbí pé ara ọmọ rẹ kò yá, gba ìdájọ́ ara rẹ gbọ́. O gbọ́dọ̀ ṣe bí:

- ọmọ rẹ bá ní ìsòro mínmín – o le s'àkìyéèsí àwọn ariwo gulegule tàbí àyà wọn tí ògiri ikùn wọn sì sákónú sí áàrin tàbí sí abẹ́ eegun àyà wọn
- ìwọ̀nyí má ńdúró nígbàtí ọmọ rẹ bá ń mín
- ara, ahọ́n tàbí àwọn ètè ọmọ rẹ bá jẹ́ àwọ̀ búlù
- ara ọmọ rẹ rọ̀ tí kòsì ní jí tàbí jí sílẹ̀



© Crown copyright 2025. Version 3. UK Health Security Agency Gateway Number 2024-944.
Product code: V2C24RSV03YO Yoruba 2p 100K FEB 2025 (APS).
To order more copies of this asset, please visit: **www.healthpublications.gov.uk** or call **0300 123 1002**.This leaflet is available as a BSL video, and audio file, in Braille, large print and translated into 30 community languages.